# ABRAHAMU ATI LỌTI

**Gẹnẹsisi 13:1-18; 18:1-8, 16-19**

**ẸKỌ 9 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: “Iwọ máṣe ilara si awọn enia buburu; bẽni ki o má si ṣe fẹ lati ba wọn gbe. Nitoriti aiya wọn ngbirò iparun, ète wọn si nsọ̀rọ ìwa-ika” (Owe 24:1, 2).**

**I Ọlọrun Ṣaaju Ohun Gbogbo**

1 Bi o ti n goke lati Egipti wá, nibi ti o ti lọ nitori iyàn ti o wà ni ilẹ Kenaani, Abrahamu sin Ọlorun ni Bẹtẹli, Gẹnẹsisi 13:1, 3, 4; Matteu 6:33

**II Ibukun Ọlọrun**

1 Ọlọrun ti bukun Abrahamu nipa ti ara lọpọlọpọ, Lọti ti o wà pẹlu rẹ̀ si pín ninu ibukun wọnyii, Gẹnẹsisi 13:2, 5; Numeri 10:29

**III Ipinya**

1 Nitori ti ẹran-ọsin wọn n pọ̀ si i, gbolohun asọ̀ wà laaarin awọn darandaran Abrahamu ati ti Lọti, Gẹnẹsisi 13:6, 7

2 Abrahamu dá amọran ipinyà, o si fi àye fun Lọti lati kọ́ yan ilẹ, Gẹnẹsisi 13:8, 9; Romu 12:18; 2 Timoteu 2:24; Jakọbu 4:10

3 Lọti fi iwà imọti-ara-ẹni-nikan hàn, Gẹnẹsisi 13:10, 11; Filippi 2:21; 1 Peteru 5:5

4 Lọti ni o padanu nitori yiyàn imọti-ara-ẹni-nikan rẹ̀, Gẹnẹsisi 13:12, 13; 2 Peteru 2:7, 8; Gẹnẹsisi 14:12; 19:14, 24-26

5 A bukún Abrahamu nitori iwa aimọ-ti-ara-ẹni nikan ti o ni, Gẹnẹsisi 13:14-18

6 A yí orukọ Abramu pada si Abrahamu, Gẹnẹsisi 17:5

**IV Iwa Iṣeni-lalejo Abrahamu**

1 Nitori ẹni iwa-bi-Ọlọrun ni i ṣe, Abrahamu fẹran alejo ṣiṣe, o si ṣe awọn angẹli ni alejo lai mọ̀, Gẹnẹsisi 18:1-8; Heberu 13:2

**V Iṣọrẹ Abrahamu pẹlu Ọlọrun**

1 Ọlọrun ṣi ọkàn Rẹ̀ payá fun Abrahamu nitori O mọ̀ pe Abrahamu ṣe e gbẹkẹle, Gẹnẹsisi 18:16-19

## ALAYE

“Abramu si là gidigidi, li ẹranọ̀sin, ni fadaka, ati ni wura.” Ni igba ayé awọn patriaki, Oluwa a maa tú ibukun ti ara jade bi ileri ohun ti ẹmi. Oluwa ti wi fun Abrahamu pe Oun yoo bukun fun un, Oun o si sọ ọ di orilẹ-ède nla; a si mu apa kin-in-ni ileri yii ṣẹ -- ṣugbọn ki i ṣe lai ni idi pataki. Ọlọrun ti wi pe, “Awọn ti o bu ọla fun mi li emi o bu ọla fun,” Abrahamu si bu ọla fun Ọlọrun; o kọ́ “tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀” nitori bẹẹ, dajudaju, gẹgẹ bi èto ti Ọlọrun ti fi lelẹ, a fi ibukun ti ara kún fun un.

Abrahamu jẹ “òtoṣi li ẹmi” o si rẹlẹ ni ọkàn. Ko gba ọrọ̀ rẹ̀ laye lati yi i lori. Bi o ti n pada bọ̀ lati Egipti, nibi ti o ti lọ nitori iyàn ilẹ Kenaani, ohun ti o kọ́ ṣe ni lati wá pẹpẹ ti o ti kọ́ ni Bẹtẹli nigba ti o kọ́kọ́ de ilẹ naa ri. O ranti Oluwa Ọlọrun rẹ̀ bi Ọlọrun ti kilọ fun awọn iran rẹ̀ ni ọpọlọpọ ọgọrun ọdun lẹyin naa.

**“Ma kiyesara rẹ ki iwọ ki o má ṣe gbagbé OLUWA**

**Ọlọrun rẹ, li aipa ofin rẹ̀, ati idajọ rẹ̀, ati ìlana rẹ̀ mọ́, ti mo filelẹ li aṣẹ fun ọ li oni:**

**“Ki iwọ ki o má ba jẹ yó tán, ki o kọ́ ile daradara, ki o si ma gbé inu rẹ̀;**

**“Ati ki ọwọ́-ẹran rẹ ati agbo-ẹran rẹ, ki o ma ba pọ̀si i tán, ki fadakà rẹ ati wurà rẹ pọ̀si i, ati ki ohun gbogbo ti iwọ ni pọ̀si i;**

**“Nigbana ni ki ọkàn rẹ wa gbé soke, iwọ a si gbagbé OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o mú ọ lati ilẹ Egipti jade wá, kuro li oko-ẹrú;**

**“Ẹniti o mu ọ rin aginjù nla ti o si li ẹ̀ru, nibiti ejò**

**amubina wà, ati akẽkẽ, ati ọdá, nibiti omi kò si; ẹniti o mú omi jade fun ọ lati inu okuta akọ wá;**

**"Ẹniti o fi manna bọ́ ọ li aginju, ti awọn baba rẹ kò mọ̀ ri; ki o le rẹ̀ ọ silẹ, ki o le dan ọ wò, lati ṣe ọ li ore nigbẹyin rẹ:**

**"Iwọ a si wi li ọkàn rẹ pe, Agbara mi ati ipa ọwọ́ mi li o fun mi li ọrọ̀ yi.**

**"Ṣugbọn ki iwọ ki o ranti OLUWA Ọlọrun rẹ; nitoripe, on li o fun ọ li agbara lati li ọrọ̀" (Deuteronomi 8:11-18).**

O ti ni lati ni ifẹ ti o muna lati jọsin ni Bẹtẹli, nitori o rin ọna jijin lati dé ibẹ̀. Ta ni ẹni naa ti kò ni fẹ́ lati kunlẹ soju kan naa nibi ti Oluwa ti gba ọkàn rẹ̀ là, tabi sọ ọkàn rẹ di mimọ́ tabi fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀ ọ? Iru àye bawọnyi jẹ́ ibi ọ̀wọ fun olukuluku ọmọ Ọlọrun.

**Ikorita Ipinya**

Lọti ọmọ arakunrin Abrahamu, ti bá Abrahamu jade ni Uri ti Kaldea. Wọn jọ lọrọ̀ ninu ẹran-ọ̀sin ati ọwọ́-ẹran to bẹẹ gẹẹ ti ilẹ̀ naa ko fi le gbà wọn, ti wọn i ba fi jọ maa gbé pọ̀, asọ̀ si wà laaarin awọn darandaran wọn.

Abrahamu, ni atetekọṣe nì ki a to kọ Bibeli paapaa, mọ̀ bi a ti i wa ni alaafia pẹlu Ọlọrun ati eniyan. Lonii a ni Ọrọ Ọlọrun:

**"Alabukún-fun li awọn onilaja: nitori ọmọ Ọlọrun**

**ni a ó ma pè wọn" (Matteu 5:9).**

**"Iranṣẹ Oluwa kò si gbọdọ jà; bikoṣe ki o jẹ ẹni pẹlẹ si enia gbogbo … onisũru" (2 Timoteu 2:24).**

**"Bi o le ṣe, bi o ti wà ni ipa ti nyin, ẹ mã wà li alafia pẹlu gbogbo enia" (Romu 12:18).**

**"Ẹ máṣe fi ìja tabi ogo asan ṣe ohunkohun: ṣugbọn ni irẹlẹ ọkàn ki olukuluku ro awọn ẹlomiran si ẹniti o san ju on tikararẹ̀ lọ" (Filippi 2:3).**

**"Ọlá ni fun enia lati ṣiwọ kuro ninu ìja" (Owe 20:3).**

Ṣugbọn awa, paapaa gẹgẹ bi Abrahamu, ni lati ni alaafia Ọlọrun ninu ọkàn wa ki a to le gbọran si itọni wọnyii.

Edè-aiyedè laaarin awọn darandaran wọnyii ba Abrahamu lọkàn jẹ́, nitori, o wi pe, "Ará li awa iṣe." O yẹ ki a tẹle apẹẹrẹ Abrahamu baba wa nipa ti ẹmi, ki a maa fi tọkantọkan "lakaka lati pa iṣọkan ẹmi mọ́ ni ìdipọ alafia," nitori ni tootọ "ará li awa iṣe."

O jẹ iwa awọn eniyan Ọlọrun tootọ lati fẹ ki awọn ẹlomiran mọ ẹwà ati titobi iwa Ọlọrun, ki awọn naa le wá mọ̀ Ọn, ki wọn fẹ Ẹ, ki wọn si le bẹ̀ru Rẹ̀. Iwe Mimọ́ sọ pe, "awọn ara Kenaani ati awọn enia Perissi ngbé ilẹ na ni ìgba na." Boya ohun gúnmọ ni pe awọn orilẹ-ède keferi wọnyii -- awọn eniyan ti kò mọ Ọlọrun – n woran ohun ti o n ṣẹlẹ. Abrahamu jowu fun ọlá ati ogo Ọlọrun. Ifẹ ati itẹriba Abrahamu fun Ọlọrun sún un lati maa lakaka nigba gbogbo lati fi iyin ati iwa rere Ọlọrun hàn ninu igbesi-ayé rẹ̀. Gẹgẹ bi Jesu ti wi pe, "Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mọ̀ pe, ọmọ-ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nigbati ẹnyin ba ni ifẹ si ọmọnikeji nyin" (Johannu 13:35).

Abrahamu dá àmọran pe ki oun ati Lọti pinya. Pẹlu iwa ọmọluwabi Abrahamu yọọda fun Lọti lati kọkọ yàn. Iba ṣe pe Lọti ni ọkàn aimọ-ti-ara-ẹni-nikan bi ti arakunrin baba rẹ̀, iba ṣe pe o ni ẹmi kan naa bi ti Abrahamu, oun i ba ti wi pe, "Baba mi Abrahamu, iwọ ni yoo kọkọ yàn. Iwọ ni àgbà, ẹtọ ti rẹ si ni lati kọkọ yàn." Ṣugbọn Lọti kò sọ bẹẹ. Ifẹ ère mu ki o doju kọ ilẹ ọlọra nibi pẹtẹlẹ Jọrdani ti o ni omi pupọ.

**Ọrọ̀**

Ọpọlọpọ ni n fi ọkàn wọn wewu fun ireti anfaani ti ara. Ifẹ lati ni nnkan ti ayé yii ati lati wà ni idẹra jẹ ọ̀na ẹ̀wẹ̀ ti ọta n gbà dán ni wò, ọmọ Ọlọrun kọọkan si ni lati ṣọra gidigidi nipa iru idanwo bẹẹ.

**"Kìlọ fun awọn ti o lọrọ̀ li aiye isisiyi, ki nwọn máṣe gberaga, bẹni ki nwọn máṣe gbẹkẹle ọrọ̀ aidaniloju, bikoṣe le Ọlọrun alãye, ti nfi ohun gbogbo fun wa lọpọlọpọ lati lo;**

**"Ki nwọn ki o mã ṣõre, ki nwọn ki o mã pọ̀ ni iṣẹ rere, ki nwọn mura lati pin funni, ki nwọn ki o ni ẹmi ibakẹdun:**

**“Ki nwọn ki o mã tò iṣura ipilẹ rere jọ fun ara wọn dè igba ti mbọ̀, ki nwọn ki o le di iye tõtọ mu” (1 Timoteu 6:17-19).**

Ọrọ̀ n tàn ni a si maa yọri nigba pupọ si awọn ẹ̀ṣẹ ti o ṣe gbagadè jù lọ.

Igbesi-ayé ti a ba jù silẹ patapata fun ifẹ Ọlọrun yoo ni awọn ẹbun ti n mu ki ọkàn ni ọrọ̀ lọdọ Ọlọrun ati lọdọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ̀. Ifẹ, iṣeun, alejo ṣiṣe, igbọran – gbogbo iwọnyi a maa mu ki igbesi-ayé Onigbagbọ kún.

**Gbigbé Oju Soke**

Abrahamu ati Lọti gbé oju wọn “si oke.” “Oju ni imọlẹ ara: bi oju rẹ ba mọ́, gbogbo ara rẹ a mọlẹ; ṣugbọn bi oju rẹ ba buru, ara rẹ pẹlu a kún fun okunkun” (Luku 11:34). Lọti gbé oju rẹ̀ si oke o si ri pẹtẹlẹ Jọrdani ti o kún fun omi, nibi ti awọn ẹran-ọsin ati ọwọ-ẹran rẹ̀ yoo ti ri koriko daradara. Ṣugbọn Abrahamu wò kọja nnkan igba diẹ ti ayé yii; o n reti ilu ti o ni ipilẹ̀, “eyiti Ọlọrun tẹ̀do ti o si kọ́.”

O ṣe e ṣe ki a ti dán Abrahamu wò lati binu pe Lọti rẹ́ oun jẹ; ṣugbọn o ni itẹlọrun ni wiwà labẹ itọju Ọlọrun. “Ẹsan ni ti emi, Oluwa wipe, Emi o gbẹsan” (Heberu 10:30). Oluwa bukun Abrahamu fun ọkàn gbigboorò ti o ni nipa fifi idi majẹmu Rẹ̀ mulẹ pẹlu rẹ̀, ati ni ṣiṣe alaye ni kikun si i nipa rẹ̀. Oluwa wi fun Abrahamu ki o gbé oju rẹ̀ soke ati lati wo iha ariwa, ati iha guusu, ati iha ila-oorun, ati iha iwọ-oorun – ati pe gbogbo ilẹ ti o ri ni yoo jẹ ti rẹ̀ ati ti iru-ọmọ rẹ̀ laelae. Lara rẹ̀ ni pẹtẹlẹ Jọrdani ti o ni omi niha gbogbo eyi ti Lọti ti yàn. Paulu wi bi o ti n kọwe si awọn eniyan mimọ́ pe, “tinyin li ohun gbogbo,… ẹnyin si ni ti Kristi; Kristi si ni ti Ọlọrun” (1 Kọrinti 3:21, 23). Oju rẹ ha n tẹju mọ kiki ogo Ọlọrun? Iwọ ha wà fun ayé yii? tabi iwọ n fẹ ni ogún pẹlu awọn ti a sọ di mimọ́ nipa igbagbọ́ ninu Kristi Jesu? Iwọ ni yoo yàn. Yàn funra rẹ.

**Orukọ Titun**

Abrahamu duro ṣinṣin ni ijolootọ rẹ̀ si Ọlọrun. Bi ọjọ ti n gori ọjọ, ninu gbogbo ayidayida ayé, o jolootọ ninu adura, o jẹ́ oloootọ lati gbọran si Ọlọrun lẹnu, lati bọ̀wọ fun ifẹ ati aṣẹ Ọlọrun. Nigba ti ipe dé lati ọdọ Ọlọrun lati “ma rìn niwaju mi, ki iwọ ki o si pé,” Abrahamu doju bolẹ lai ṣe aniani pẹlu yiyọọda ayé ati ifẹ rẹ̀ ni kikún fun Ọlọrun. Ọlọrun si ṣi majẹmu Rẹ̀ paya ni kikún si i nipa sisọ pe, “Iwọ o si ṣe baba orilẹ-ède pupọ̀,” O si yi orukọ rẹ Abramu, itumọ eyi ti i ṣe “baba giga” si Abrahamu, itumọ eyi ti i ṣe “baba ogunlọgọ”. (Wo Iwe Kẹtala Ẹkọ 157).

**Ṣiṣe Alejo**

Nitori igbẹkẹle Abrahamu ninu Ọlọrun, ẹni ti o ni gbogbo ẹran ti ó wà lori ẹgbẹrun oke, ti ẹni ti gbogbo fadaka on wura si i ṣe, oun naa ni ọkàn ipinfunni; nigba ti o si gbé ojú rẹ soke bi o ti joko lẹnu ọna agọ rẹ̀ ni pẹtẹlẹ Mamre, o ri awọn ọkunrin mẹta n bọ̀ wá si ọdọ rẹ̀, o si sare lọ pade wọn. O ṣilẹkun ọkàn rẹ paya o si gbà wọn tọkàntọkàn. O yara lati tù wọn lara nipa fifun wọn ni omi lati wẹ ẹsẹ̀ wọn, iwa ọmọluwabi ti a n fi hàn fun awọn arinrin-ajo ni ọjọ wọnni nitori bata jalawọọta ni wọn n wọ̀, wọn si n rin lọna eleruku. O ni ki Sara yara mu oṣuwọn iyẹfun mẹta ki o si din akara lori iná. Lẹyin naa ni o sure lọ sinu agbo o si mu ẹgbọrọ maluu daradara kan (ki i ṣe ọ̀kan ṣá) o si fun ọdọmọkunrin kan lati se e ati lati tọju rẹ̀ fun jijẹ. Nigba ti ohun gbogbo ṣetan o lọ si ibi amu rẹ̀ o si mu ori-amọ ati wàra wá. Ounjẹ yii ti gbadun to – gbogbo rẹ̀ fun awọn alejo! “Ẹ máṣe gbagbé lati mã ṣe alejò; nitoripe nipa bẽ li awọn ẹlomiran ṣe awọn angẹli li alejò laimọ̀” (Heberu 13:2). Nibomiran Ọlọrun sọ fun ni pe ki a maa ṣe alejo lai si ikunsinu.

Ka ohun ti Jesu wi: “Nigbati Ọmọ-enia yio wá ninu ogo rẹ̀ … Nigbana li Ọba yio wi fun awọn ti o wà li ọwọ́ ọtun rẹ pe, Ẹ wá, ẹnyin alabukun-fun Baba mi, ẹ jogún ijọba, ti a ti pèse silẹ fun nyin lati ọjọ ìwa: nitori ebi pa mi, ẹnyin si fun mi li onjẹ …” (Matteu 25:31-36).

Apẹẹrẹ alejo ṣiṣe pọ̀ ninu Bibeli. Marta ṣe Jesu ni alejo ni ile rẹ̀. Lidia rọ Paulu ati awọn ẹgbẹ́ rẹ̀ lati wọ̀ ni ile rẹ̀. Lẹyin ti onitubu ni ilu Filippi ri igbala, o mú Paulu ati Sila o si wẹ ọgbẹ́ wọn, o si mu wọn wá sinu ile rẹ̀, o si gbé ounjẹ ka iwaju wọn, o yọ̀, o si gba Ọlọrun gbọ́ pẹlu gbogbo ara ile rẹ̀. Jesu wi pe “Ọfẹ li ẹnyin gbà, ọfẹ ni ki ẹ fi funni” (Matteu 10:8).

**Ayọ̀ Irẹpọ̀**

Abrahamu yọ̀ lati ni ibẹwo lati ọdọ awọn alejo ode-ọrun wọnyii. A kò mọ̀ bi o ti yá to ki o to mọ̀ pe awọn ẹni mẹta wọnyii ju eniyan lasan lọ. Ṣugbọn a mọ̀ pe ki wọn to lọ o mọ iru ẹni ti awọn alejo yii i ṣe. I ha i ṣe Oluwa funra Rẹ̀ ni o ṣe lalejo? O ṣe e ṣe ki ọ̀kan ninu awọn “ọkunrin” naa jẹ́ Ẹnikeji ninu Mẹtalọkan ti o sọkalẹ wá jiròro pẹlu Abrahamu.

O ni lati ni “igbona ọkàn ti o yatọ” laaarin ẹgbẹ́ ọrun bayii. Nigba ti Jesu fara hàn fun awọn ọmọ-ẹyin meji ni ọna Emmausi, ojú wọn kọ́kọ́ di, ṣugbọn nigba ti o ti fi ara Rẹ̀ hàn wọn, wọn wi pe, “Ọkàn wa kò ha gbiná ninu wa, nigbati o mba wa sọ̀rọ li ọ̀na?” (Luku 24:32). Ni tootọ ọkàn wọn gbina pẹlu ifẹ mimọ́ nigba ti Jesu fi ara Rẹ̀ hàn wọn.

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni Abrahamu lọ ni gẹrẹ ti o dé lati Egipti?
2. Nitori ki ni?
3. I ha i ṣe Abrahamu, tabi Abrahamu ati Lọti ni o ké pe orukọ Oluwa?
4. Iṣoro wo ni o wà laaarin awọn ọkunrin meji yii?
5. Iru ihà wo ni Abrahamu kọ si ohun ti o ṣẹlẹ naa?
6. Bawo ni Lọti ti ṣe?
7. Ta ni Oluwa fara hàn, Abrahamu tabi Lọti?
8. Ta ni gba ibukun?
9. Irú awọn eniyan wo lode oni, ni o n tẹle igbesẹ Lọti?